**ALAYE LORI**

**Ipo Ti Awon Ohun Ogbin Imo-Ero Ti O Ye Fun Tita Wa Lagbaye: Ti Odun 2011**

**Onkowe Ni Clive James, Ti O Je Oludasile Ati Alaga Ajo ISAAA**

**A ko eyi fun billionu kan alaini pelu awon ti ebi npa lati le doola la emi won**

## Saare ohun ogbin imo-ero n goke si leyin odun meedogun leralera pelu bi iye awon enia lagbaye se n sunmo billion meje

Idagbasoke to wuyi to tesiwaju ni odun 2011, latari awon anfaani ti o ro mo eto ohun ogbin imo-ero ni o se gbe peeli ni iwon bi saare million mejila to tumosi ida mejo ninu ogoorun lodoodun, ti o si nto bii million ogoojo(160 million)saare oko, lati iwon meji-din-laadojo milionu (148million)saare ni odun 2010.

Gigoke si ni ilopo merin-le-laadorun lati milionu kan abo-le-lugba(1.7 million) saare ni odun 1996 si ogoojo milionu saare ni odun 2011, mu ki awon ohun ogbin imo-ero igbalode yi di, ona itewogba lati maa lo imo-ero fun ohun ogbin ninu itan.

Eri ti odaju nipa eto yii ni pe laarin odun 1996 si 2011, ogunlogo awon agbe lagbaye se ipinu ti o ju ogoorun milionu meedogbon nipa ifokanbale ti won ni ninu eto imo-ero yi, wipe awon ohun ti a ba gbin ni ona imo-ero igbalode yi maa ntojo, o si maa n se anfaani fun oro aje ati ayika ibi ti a ti gbin.

Awon orilede mokandinlogun ti o sese ngoke, ati mewa ti o nilese nlanla ninu orileede monkandinlogbon ni o sogbin lona imo ero igbalode yii ni odun 2011. Okookan ninu awon mewa akoko ni o sogbin ju milionu saare kan lo, ti won si fi ipile oniruuru ona lati sogbon lojo iwaju lagbaye lele.

Million merindinlogun ati eedegberin (16.7 milionu) awon agbe ni o fi imo-ero sogbin ni odun 2011, awon odunrun-le-ni milionu kan, tabi ida mejo ninu ogoorun ni o lo ilana yi ni odun 2010- awon ti o ju ida aadorun ninu ogoorun tabi milionu meedogun ni o je awon agbe kereje, ni awon orileede ti o sese ngoke agba, awon agbe yii naa ni won mo ona lati gbe ewu fo lori eto ogbin, atipe, ni odun 2011 akosile fihan pe milionu meje awon agbe kereje ni orileede China ati iye milionu kan naa ni India, ni won yan lati gbin owu Bt sori saare oko milionu merinla o le eedegbeta.

Awon orilede ti o ngoke se idaji ogbin won pelu eto ogbin imo-ero kariaye ti biotech ni odun 2011 ti o si ye ki won tayo iye saare awon orileede ti o nilese ni odun 2012. Ni odun 2011 sisogbin pelu imo ero (biotech) tun yara si ni ilopo meji ni awon orileede ti o sese ngoke,pelu ida mokanla ninu ogoorun tabi milionu mejo lerugba saare ti a ba fi we ida marun ninu ogoorun tabi milionu mefa ati egbeta saare ti awon orileede ti o nilese.

Ona ti olukuluku ngba se ogbin tire se Pataki, awon orileede mejila ni o ogbin awon ohun ogbin imo ero(Biotech) ni ona ara ni odun 2011, ti mesaan ninu mejila je orileede ti o n goke-ida merin tabii milionu mejilelogooji ati igba saare ninu ogoojo ni a ko jopo ni odun 2011, lati mejilelogbon milionu o le oodunrun tabi ida mejilelogun ninu ogoorun saare ninu mejidinlaadojo milionu saare ni a ko jo ni odun 2010.

Awon orileede marun ti o n gbegba oroke ninu awon ti o n goke nipa lilo eto ogbin imo-ero ni orileede India ati China ni Asia, Brazil ati Agentina ni Latin America, ati gusu Africa (South Africa) ni ile Adulawo ti won duro fun ida ogooji ninu ogoorun gbogbo agbaye ti o le to bilionu mewa o le milionu kan ni odun 2100.
Larin odun meta leralera ni orileede Brazil ti je ibi ti eto ogbin imo-ero yi ti jinle nipa pipo saare oko won ti o ju ti orile ede miran lo- pelu milionu merin ati eedegbesan saare, lati ida ogun ninu ogorun ni odun 2010.Ilana kan sagbekale awon ohun elo tuntun meta bii: ewa ti kokoro arun ko lee kolu ti a gbin ti a se agbekale re lati owo awon ara ilu pelu ifowo-so-wopo EMBRPA(Brazilian Agricultural Research Cooperation).

Orileede US ni o n leke laarin awon ti o n pese ohun ogbin imo-ero biotech lagbaye pelu milionu mokandinlaadorin saare, ti bii ida mesan ninu mewa gbogbo awon ohun ogbin imo-ero, gbigbin RR'alfalfa' beere pelu bii egberun lona igba saare pelu egebrun lona irinwo-le die ti o je ti RR Sugarbeet. Orileede US ti

fowosi jije Ibepe ti kokoro arun ko le ba ja, yala gege bi eso tabi ounje imooyo ni orileede Japan, beere lati osu kejila odun 2011.

Orileede India sayeye ajodun odun kewa gbingbin owu Bt, nipa gbingbin tayo milionu mewa saare fun igba akoko, o tile to egbeta-le-ni milionu mewa saare, ti o gba ida mejidinlaadorun ninu ogoorun milionu mejila-le-logoorun saare oko owu. Awon ti o je anfaani julo ninu gbingbin owu je awon agbe kereje bii milionu meje ti won fi saare oko milionu kan abo sogbin owu. Owo ti orileede India nri lori gbingbin owu Bt gbe peeli si laarin odun 2002 si 2010 pelu bilionu mesan-le-ni irinwo milionu Dola ati bilionu meji abo ni odun 2010 nikan.

Ni orileede China, milionu meje awon agbe kereje ni won gbin owu Bt sori saare oko ti o to milionu meta-o- le eedegberun ti o je ida meje o le die ninu ogoorun. Yoo je anfaani fun orileede China ti Iresi goolu(Golden rice) ba le di tita ni Phillippines ni odun 2013 si 2014.

Orileede Mexico sogbin owu lona imo-ero ti o to egberun lona ogoorun kan abo ati eedegbeta saare oko ti o tumosi ida mejo ninu mewa pelu egberun mejidinlogoota ni odun 2010. Eyi je akitiyan lati ni owu lopo yanturu ati lati gbin agbado lona imo-ero ni awon ipinle ariwa, ati lati san milionu mewa apo oka ti o je ele owon gogo eyi ti a ra lati ile okeere wa.

Orileede Adulawo te siwaju ni ibamu pelu alakale eto ogbin imo-ero yii. Orileede Gusu Afrika, Burkina Faso ati Ijibiti pelu sogbin bii saare oko milionu meji abo, Kenya, Nigeria ati Uganda je orileede meta ti o ti gbidanwo ogbin owu.

Nigbati orileede alawo funfun mefa sogbin Agbado egberun lona ogoorun kan-le ni irinwo saare, ti o je bii ida meta ninu mewa ni odun 2010, pelu orileede meji miran ti o gbin anamo ni ona imo-ero ti a pe ni 'Amflora'.

Eto ogbin imo-ero yii ko ipa Pataki ninu yiyi oju ojo pada ati lati mu ki ounje wa ni opo yanturu ni odun 1996 si 2010, nipa sisafikun ohun ogbin ti o to bilionu meji-din-logoorin Dola o le milionu merin, ti o n se anfaani fun ayika; nipa didin lilo oogun apako ti o to iriinwo kilo ku ni odun 2010 nikan, eefin oloro dinku ni iwon bilionu mokandinlogun kilo nipa kiko oko ti o to milionu mesan kuro ni oju popo, ati pipa awon oun abemi mo latari dida abo bo milionu mokanle-laadorun saare ile; bakanaa o din aini ku nipa riran awon agbe kereje bii milionu meedogun ti o wa lara awon ti o kuse julo lagbaye lowo. Awon ohun ogbin imo-ero dara sugbon won kii se ona abayo si sise agbe daradara bii ti akore-daresi ti atijo se se Pataki fun ohun ogbin miran ju ti imo-ero lo.

O ye ni kiakia pe ki a fi aye gba eto imojinle sayensi to moyan lori ti ko ni na ni lowo tabi gbani lakoko eyi ti awon orileede kekeeke ti aini nbaa finra pelu awon ti o sese n goke agba ati fun awon alawo funfun.
Iye Eso ogbin imo-ero lagbaye to bilionu metala Dola ni odun 2011, pelu Oka ti a pese ni ona imo-ero ti o to ogoojo bilionu Dola lodun.
Agbekale ojo iwaju MDG fun odun 2015 ati lehin igba naa dabi I pe yoo so eso rere pelu afikun bii orileede mewa tuntun miran, Agbado ti eerun kii baje ti a pese lona imo-ero biotech ni won yoo pin fun orileede Ariwa Amerika ni odun 2013 ati Adulawo(Africa) ni 2017; ati Iresi Goolu(Golden Rice)ni Philippines ni odun 2013 si 2014; bakanaa Agbado imo-ero ti yoo le gbin to ogbon milionu saare, ni yoo di pinpin ni orileede China, leyinaa ni a o pin Iresi Bt. Awon ohun ogbin imo-ero yii tun ko ipa Pataki ninu alakale eto MDG ni odun 2015 nipa dindin osi ku ni iwon idaji, ati pipese ohun ogbin eyi ti won yoo se pelu ifowo-sowopo awon ara ilu ati aladani bii: agbado ti eerun kii baje ti o wa fun orileede Adulawo se je iranlowo lati odo oninuure bii Bill ati Melinda Gates.

Diduro lori sisafihan imo ISAAA pelu awon orileede bii meta, agbekale ati Ogbon ti won fi n baa awon enia lo da lori aba sise je ti ajo ti Gates je oludasile re fi ranse si G20 ni osu kokanla odun 2011.

Ekunrere alaye wa ni ISAAA Brief 43 "Ipo Ti Awon Ohun Ogbin Imo-Ero Ti O Ye Fun Tita Wa Lagbaye Ti 2011" ti Clive James ko. Fun ibeere e wo ori ero ayelujara wa ni http://www.isaaa.org tabi ki o kan si ISAAA AfriCenter pelu nomba yii +245 20 4223618 tabi africenter@isaaa.org tabi info@isaaa.org.